Bibeli fun awon omode

# Peteru ati Agbara Adura



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Janie Forest
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Aposteli Peteru lo kaakiri orile-ede lati so fun elomiran nipa Jesu; Ni ojo kan, ni ilu ti a pe ni Lydda, o ba eni kan pade ti o wa ni ori ibusun, o yaro fun odun mejo. “Jesu Kristi wo o san,” Peteru so bee. “Dide ki o sigbe akete re.” Okunrin naa si dide lesekese. Awon eniyan ti won ri eyi si yipada si Oluwa.





Ni bi ti ko jinna si Joppa, awon eniyan banuje. Omobinrin onigbagbo kan ti oruko re n je Dokasi sese ku. Pelu ibinuje awon ore re n palemo lati sin in, won gbe e si ibi kan ni yara oke nibi ti won ti n sofo.



Sugbon awon ore Dokasi gbo pe Peteru wa ni agbegbe naa. Won pe Peteru ki o maa bo ni Joppa nisinsinyii.  Nigba ti o wa ni yara oke, awon opo n fi ewu ati aso ti Dokasi da han won. Gbogbo won n so kun.

Sugbon Peteru ti gbogbo won sode, O kunle o si gbadura. O si' yipada si' Oku naa o so'pe, "Dokasi, dide." O si ya oju re, nigba ti o si ri Peteru O dide joko.





O si na owo re, o si gbe dide, nigba ti o si pe awon mimo (Kristiani) ati awon opo, o fi ara le won lowo laaye. O si di mimo ka gbogbo joppa. Opo eniyan gbagbo ninu oluwa.

Peteru sigbe ojo pupo ni Joppa, ni inu ile kan legbe okun. Ni ojo kan Peteru lo si ori oke lati gbadura. O le ti wo awon opo ilu,

o le ti ri awon arinrin ajo meta ti won waa wa.





Awon okunrin naa je iranse olori ogun Romu ti oruko re n je Koniliu eniti n nsin Olorun. Koniliu ran awon iranse lati wa Peteru nitori awon angeli so fun un loju iran, "Ranse si Peteru. O n se atipo pelu Simoni, alawo eniti ile re wa 'legbe okun. Yio so ohun ti iwo yoo se fun o."

Nigbati Peteru n gbadura loke ile, Olorun fi iran kan han an. O dabii pe ohun elo kan ti o dabii gogowu lori ile aye. Lori re ni awon eranko ati eye. Peteru wi pe' alaimo ni awon wonyi. Eyi tumo sipe Olofokansin Juu ko gbodo je e. lojiji, ohun kan wa wi pe "Dide, Peteru, pa ki o si je."



“Koribe, Oluwa” Peteru wi fun Olorun “Nitori emi ko je ohun eewo ati alaimo kan ri.” Ohun kan situn to o o wa leekeji. “Ohun ti Olorun ba ti wenu iwo mase pe e li eewo mo.” Eyi waye ni igba meta. A sigbe ohun eelo naa pada lo si oke orun.



Oye iran yii ko ye Peteru.  Bi o se n ronu nipa re, Olorun so fun pe awon okunrin meta n waa ati pe ko lo pelu won.  Nigba ti awon okunrin meta naa so fun Peteru pe angeli mimo so fun Koniliu ko ranse si o, Peteru mo pe Olorun n dari oun.  Ni ojo keji, oun ati ore re, mefa lo si ile Koniliu.





O si se, bi o ti lo ni oju ona re si ile eni ti k ii se Juu, Peteru bere si ni oye pe Olorun feran gbogbo eniyan – ati pe Olorun feran ki gbogbo orile-ede mo pe Jesu ni Olugbala araye. Nigba ti Peteru de be, Koniliu foribale o sin niwaju re.

"Dide duro, Eniyan ni emi tikarami" Peteru so fun Koniliu. Leyin naa o so fun gbgogbo eniyan ti o wa ninu ile, "Eyin mo bi o ti je eewo fun eniyan Juu lati kegbe po tabi lati lo si ori lede miran." "Sugbon Olorun fihan mi pe ki o mase pe enikeni ni eewo tabi alaimo."



Peteru wi fun awon keferi (tii ki I se Juu) pe Jesu je omo Olorun, eni ti o ku lori igi agbelebu ti o si jinde lati je Olugbala araye. Nigba naa ni Emi Mimo ba le won, won si n yin Olorun. Enu yaa Peteru ati awon ore re Juu mefefa. O dabi Pentikos. Ebun Emi Mimo si wa sori awon alaigbagbo. Leyin naa Peteru Baptisi awon ti asese gbala ninu Jesu.



Ni Jerusalemu awon Kristiani bu enu ate lu Peteru fun bibe awon keferi wo. Nitori naa Peteru wi fun nipa iran ti ohun ati Koniliu ri ninu adura. Nigbati won gbo nnkan wonyii, awon kirisitiani Jerusalemu dakee je. Won si fi ogo fun Olorun, Eni ti o fi han gbogbo ijo Kritiani pe Olorun feran gbogbo eniyan.



Peteru ati Agbara Adura

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Ise awon aposteli ori kesan si ikejila

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun
iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe:
Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo!
Johannu ori keta ese kerindinlogun.